Drink Coca-Cola
STANDARD SIZE 4D
NEW KING SIZE 6D

Irohin Yoruba

Vol. XII No. 574 JUNE 11 – JUNE 17, 1956 KOBO KAN 1(d)

Oyo-e Infants' Preparations
Gbogbo awọn Abiyamọ ... 
The Premier Trading Co. Ltd.
P. O. Box 227 Ibadan.
A wle Amaja Ajagbeta

# AWOLỌWỌ TUN BỌ S'AYE ALAKOSO IJỌBA IWỌ-ORUN



Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ nfi ọwọ si iwe adehun aṣẹ alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ni afin Gomina Ipinlẹ Iwọ-Orun ni Ibadan pe on gba on si pinnu lati tun sin awọn orilẹ ede ilu on fun ọdun marun si i gẹgẹbi Alakoso Ijọba. Ki Ọlọrun pẹlu rẹ ati awọn emẹwa rẹ. Amin.

IBADAN

**Laisi ani-ani Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Ọga ;un Ẹgbẹ Afẹnifẹre ( Action Group ) yio tun lo aye Alakoso Ipinlẹ Ijọba Iwọ—Orun ịẹkan si.**

Ni ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu yi ni Gomina Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria, Ọlọla John Rankine ati Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ṣe ipade pataki kan pọ lori eto Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Iyọris ipade na ni pe Gomina na tun yan Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ lati tun wa ni aye Alakoso Ipinlẹ Ijọba Iwọ-Orun Naijiria fun ọdun marun si, fun lileke ti awọn Ẹgbẹ rẹ leke ninu ibo ti nwọn di koja yi. Gomina na si sọ pe ki Oloye Awolọwọ lọ yan awọn Iriju Igbimọ (Ministers) rẹ ki o mu won wa han on.

Ni ọsan ọjọ 'Bọ ti iṣe ọjọ keje oṣu yi ni Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun yan awọn Minista rẹ ni Ile Ijọba (Government House). Lati aro ọjọ na ni ọpọlọpọ ti ndoyi Ile Iṣẹ Ijọba ti nwọn nfi eti l'oko pẹlu iwarapapa lati mọ awọn ti yio jẹ Minista na. Iyipada diẹ ni o wa ninu yiyan awọn Minista na, si ti eyi ti o ti koja.

Awọn Minista mẹwa ni Alakoso na si yan pẹlu ara rẹ. Nwọn pin ipo Alabojuto Ofin Igbimọ Ijọba Ibilẹ (Minister of Local Government) si meji. Awọn Minista na ni wọnyi ati iṣẹ ti a gbe le onikaluku won lọwọ lati ṣe alabojuto rẹ:—

Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ—Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun.

Ọgbẹni D. S. Adegbenro—Minista (Alabojuto) Ilẹ ati Iṣẹ (Labour).

Ọgbẹni A. O. Adeyi—Alabojuto Ijọba Ibilẹ.

Oloye C. D. Akran—Alabojuto Idagbasoke.

Oloye G. A. Dẹkọ—Alabojuto ohun Ọgbin ati ohun Ilẹ.

Oloye Tony Enahoro—Alabojuto awọn ọran Igboro Ilu.

Ọgbẹni A. O. Ogedengbe Alabojuto Iṣẹ (Works).

Ọgbẹni J. A. O. Odẹbiyi—Alabojuto Eko.

Ọgbẹni A. Okusaga—Alabojuto Ilera.

Ọgbẹni J. O. Oshuntokun—Alabojuto Owo.

Oloye F. R. A. Williams—Alabojuto Idajo-Ododo ati Igbimọ Ijọba Ibilẹ.

Ilu ti awọn alabojuto (Minista) ti wa ṣe aṣoju Igbimọ niyi: Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun lati Ekun Ijẹbu-Rẹmọ, Rotimi Williams Aṣoju Pataki lati inu Igbimọ Oloye, D. S. Adegbenro lati Ekun Ilu Ẹgba; Tony Enahoro lati Ishan, C. D. Akran lati Badagiri, J. A. O. Odẹbiyi lati Ẹgbado, A. O. Adeyi lati Ọyọ, G. A. Dẹkọ lati Ondo, A. O. Ogedengbe lati Ọwọ, A. Okusaga lati Ijẹbu-Ode ati J. Oshuntokun lati Ekiti. Oluwa pẹlu wọn ki O jẹki Ijọba wọn na ... ma a ṣe wa ni anfani siwaju ati siwaju.

## Ẹjọ Adelabu bẹrẹ ni Kotu Ganran

IBADAN.

EJỌ riba ponun medogbon ti Ijọba mba Adegoke Adelabu ṣe bẹrẹ ni Kotu Ganran ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ karun oṣu yi. Ninu oṣu kẹrin ọdun yi ni Adajọ Kotu kekere taari ẹjọ na si Kotu Ganran (Assizes). Kulẹ-kulẹ ẹjọ na ni pe Adelabu gba ponun medogbon lọwọ Ladejọ Amao ati James Ogunshola, pe on (Adelabu) yio fi enikini si enu iṣẹ aṣọgbo (Forest Guard), on yio si fi enikeji si enu iṣẹ Akọda; ko si mu ileri rẹ ṣe lẹhin ti o ti gba owo na tan lọwọ won.

Nigbati nwọn tun bẹrẹ ẹjọ yi ni Kotu Ganran ni Samuel Ogunsola, eni adọrin ọdun, ti Abule Ogunrin, Ibadan ti ro ẹjọ pe Adelabu sọ fun on pe on moorin ati pe aye kan ṣi silẹ fun iṣẹ Akọda; meji si ṣi silẹ fun iṣẹ aṣọgbo. O ni ohun ti o mu on lọ ba Adelabu ni pe awọn meji ninu awọn ọmọ on ko si l'enu iṣẹ, on si gbọ pe aye wọnyi ṣi silẹ ati pe Adelabu ni o le gba enia fun awọn iṣẹ na nitori on ni o wa ni Alaga Igbimọ Ijọba Ibilẹ Ibadan nigbana.

O ni Adelabu gba ponun mẹwa lọwọ on lati fi ọmọ on, James Adigun si aye aṣọgbo, ati pe on fi ponun medogun ti o bere fun ran Ali Oyebanji si i ki o ba gba Adeleke Alamu si aye Akọda. O ni Oyebanji paapa gba ponun kan lọwọ on, gẹgẹ bi aye alarina ti o wa larin on ati Adelabu.

O ni nitoripe on wa ninu Ẹgbẹ Alakuko (NCNC) ninu eyi ti Adelabu jẹ ogagun kan ni on ṣe wa iranwọ yi lọ si ọdọ rẹ, o si ṣe alaye pe on si fi ẹsẹ mulẹ ninu Ẹgbẹ Alakuko na, on ko si ni ero lati wọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group.)

Ọgbẹni T. A. B. Oki ni agbẹjọro Ọba, Ọgbẹni Dingle Foot ni lọya Adelabu. Nwọn ṣi wa l'enu ẹjọ na. Bi nwọn ba ti pari rẹ si, ẹ o ma a gbọ o.

## Niuu odun yi ni nwọn a tu Igbimọ Ijoba Iha Ariwa ka

NI ọjọ Ru ti iṣe ọjọ kẹta oṣu kẹta ọdun yi ni Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa Ọlọla Alhaji Ahmadu, Sardauna Ṣokoto kede ni Kaduna pe Ẹgbẹ Northern People's Congress gba Gomina Ipinlẹ Ariwa, Ọlọla Bryan Sharwood-Smith ni imọran pe ki o tu Igbimọ Ijọba Iha Ariwa to wa nisisiyi ka ki ọdun yi to pari.

Ẹgbẹ Northern People's Congress na yio si tun ba Gomina na jiroro pe ki o ṣe eto lati di ibo tuntun fun Igbimọ Ijọba Iha Ariwa na larin igba ẹrun ti o mbọ yi eyi ti nwọn yio fi ọjọ si laipẹ.

Sardauna Ṣokoto si tun fi kun un bayi pe, Ijọba Ipinlẹ Ariwa ti ngbero ni



SARDAUNA ṢOKOTO

iwọn oṣu diẹ sẹhin ... imura silẹ lati ṣe ofin ... idibo tuntun fun awọn aṣoju ti a o dibo fun wọle Igbimọ Ijọba Iha Ariwa.

O ni ọkan on balẹ pe awọn ara ilu Ipinlẹ Ariwa yio faramọ gbogbo eto ofin titun na fun idibo na.

O si pari ọrọ rẹ pẹlu alaye bayi pe on ṣe ikede yi lati fi han gbogbo enia nitori ẹlomiran ti o ngbọ ọrọ na sodi pe nitoripe Ẹgbẹ Northern People's Congress yan ọdun 1959 sọtọ gẹgẹ bi ọdun afojuda fun gbigba ominira fun Ipinlẹ Ariwa nitorina ki yio si idibo fun Ile Igbimọ Ijọba Iha Ariwa titi ti ọdun na yio fi pe.

MAA KA IROHINYORUBA

★ ★ ★ ★ ★ ★


# AWON OGBOLOGBO (SCRAP)

OJE (LEAD)
IDẸ (BRASS)
BABA (COPPER)
AWỌN ALOKU IRIN
ẸRỌ MỌTO (RADIATORS)
PAANU AYỌ (ALLUMINIUM)

# JE OWO

**Ko wọn wa ta fun**

**BUCK (NIGERIA) LTD..**

2, AERODROME ROAD, APAPA.
TELEPHONE
55177.





Awọn ibatan yi ni . . . . Akọ-iba



Awọn ibatan yi lo

**'DARAPRIM'**



Iyọ koro kan l'ọsẹ kan m'ara wọn le !

Dabobo awọn ẹbi rẹ lọwọ Akọ-iba atipe ki o ran awọn ọmọ rẹ lọwọ lati dagba dada ki nwọn si le lagbara. Awọn agbalagba olo koro kan 'Daraprim' kan l'ọsẹ kan, ọmọ ti o ba dagba kọja ọdun marun, idaji koro, ti ko ba dagba to ọdun marun, idamerin koro. 'Daraprim' ko ladun lẹnu ko si nyi enia lawọ ara pada.

**O gba'nia laju, o daju ju, owo rẹ si dinku.**

THE MARK OF BURROUGHS WELLCOME & CO.

Agents for British West Africa: I. L. MORISON, SON & JONES (NIGERIA) LTD., LAGOS
I. L. MORISON, SON & JONES (GOLD COAST) LTD., ACCRA




CHIEF C. D. AKRAN
Minister of Development



CHIEF F. R. A. WILLIAMS
Minister of Justice and Local Government.



MR. A. OSHUNTOKUN
Minister of Finance



CHIEF G. AKIN DEKO
Minister of Agriculture



MR. A. OKUSAGA
Minister of Health



MR. D. S. ADEGBENRO
Minister of Land and Labour



CHIEF ANTHONY ENAHORO
Minister of Home Affairs



MR. A. O. OGEDENGBE
Minister of Works



CHIEF J. A. O. ODEBIYI
Minister of Education

★ ★ ★ ★ ★ ★

Ọgbẹni A. O. Adeyi nikan ni kosi aworan re nibẹ.





[illegible]

Issued by the Western Nigeria Information Service



# Ninu Ikanju, pe TAKISI OPẸLI
# Pe FẸLẸLẸ yio tete gbe ọ de ibẹ


Printed by the Amalgamated Press of Nigeria Limited 5/7 Apongbon Street, Lagos. Editor: S. M. Ademuyiwa, 9 Chapel Street, Lagos.

Lati ọwọ Kotannawọla Opẹbiyi

# AZIKIWE NLOYUN IYANGBO

ANI so pe Dokita Azikiwe ... fe awon Yoruba fun ire ... oye lati mu won je agesi ... apọnmi fun awon Ibo? ... wipe Egbe Alakuko ... si Egbe "Ibilu tabi ... ti awọn Onigbogbo ... pe ti "Egbe Eru"? Tani ... aimoye na ti ko ri apere ... ibanuje lara Azikiwe? ... iyesi okunrin na, ọkan re ... fun Ibi. Azikiwe ... sugbon ewe, oniwa jamba ... enia."

Mo ki awon enia Ipinle Iwo-Orun ku orire pe Egbe Alakuko ko le ri ipa kan sa lori ijoba won. Ipin yi ko le mo titobi ajo to so mo egbon Egbe Afenifere lori Dokita Azikiwe to fe fi ohun-ini Yoruba se ikogun fun awon Ibo. Mo tun ki awon omo Yoruba ti oye ye ti a si owa ire ati ifokanbale orile-ede Yoruba ku ajaye.

Sugbon mo niiati so fun won nihin pe ija idibo ti dopin, sugbon ogun Egbe Alakuko koi ti pari—"ija ilara ko tan bere"—Azikiwe si nrobi ninu ki a fika lati pin ile Yoruba fun awon Ibo, ati lati se gege le ohun-ini awon ti "Oluwa ko jusi se lore."

Ko si aimoye kan, yala lati Ila-orun tabi lati inu Egbe Awokoya, ti o le so fun wa bi wahala ati iponju awon enia Ipinle Iwo-orun iba ti po to bi o ba jepe agbara ijoba bo si owo Azikiwe ati awon omo ogun re, "Egbe Alakuko, jibiti parapo." Sugbon awon ologbon ti beresi ri oye eto buburu ti Azikiwe nse fun iteba ati ituka orile-ede Yoruba ti ko gba gbere fun Nnamdi (Okunrin, anibaba) lati tan agbara ati iwa pakanleke awon Ibo sori ilu Naijiria.

Ibasepe Egbe Alakuko rase rinle ki awon si gba ijoba) wahala iba ba awon oba ati ijoye ile Yoruba. Boya Azikiwe iba ti fi ade Oba fun Orisa Arosuku, tabi ki opa ileke ti di igi-idana fun awon Ibo. Daju-daju, Oloye Awolowo, Akintola ati awon ...ala pataki-pataki ninu Egbe Afenifere iba ti di mimuso bi eran agutan. Eyi kiise ahesọ tabi idunrunmoni oro. O ti farahan ninu iwa awon Ibo.

Otito ti jade lenu awon omo Egbe Alakuko; ohun ti ngele kakiri ti fihan, pe irora awon omo Egbe Afenifere ati awon to feran alafia ati ifokanbale ile Yoruba iba po ju ti obinrin ti nrobi. Gbogbo Ibo nibigogbo lo ti mura sile lati fi "jonganna" gbe gbogbo awon ti ko ba se ti Azikiwe. Sugbon lọgun Egbe Awolowo ti fi gbogbo won sinu ofo nla; Oluwa ti so imoran won, bi ti Ahitofeli, di asan. Azikiwe bi eniti nkigbe ninu aginju ibanuje, ti nwa ona miran lati pa kadara da. Ẹ kiyesi Azikiwe, ota alafia ile Yoruba!

Dokita Azikiwe ninu ipohunrere ekun re ti fihan pe enu lasan ti on fi nkigbe irepo Naijiria. Okan re ko fe irepo. Kini ami irepo to wa lara eniti nfe ota sarin awon Yoruba lati so ile won dahoro? Nigbati ireti re, bi ti Hitila, saki, ti o si ripe "ibinu Oluwa ba le awon to korira alafia awon enia re," Azikiwe pinnu pelu egbe re lati pin Ipinle Iwo-orun si ona meta ni ireti pe nipa sisebe on yio gbe ilu dide si ilu, ijoba si ijoba, Yoruba si Yoruba, on yio si ko won leru nikehin. Sugbon ope ni fun Olorun ti o mu Azikiwe ati egbe re subu.

Nitoto, Azikiwe, bi Lusiferi, subu, a si fi itiju ati abuku wo on ati Egbe Alakuko laso, sugbon alafia ati ifokanbale ile Yoruba si wa ninu ewu, afi bi gbogbo wa ba gbarajo fi agala ti elemele si Ipinle Ila-orun, ki a si takete si egbe irunbi—Egbe Alakuko ti Azikiwe gbekale nitoriti ire kan ki yio ti inu re jade fun ile Naijiria. Azikiwe li ota repo Naijiria. Egbe Esu li Egbe Alakuko. Ekun ose ati abamo li ere awon to ba faramo Egbe Azikiwe. Koi ba nfe ri ire Oluwa ni ile alaye gbodo yago fun Egbe Alakuko to nsefefe ninu iwa buburu.

Dokita Azikiwe ninu ibanuje re so fun wa pe Egbe Afenifere yio fiya je awon Oba ati Ijoye ati pe awon Oba ati Ijoye nse atilehin fun Egbe Afenifere lati bori Egbe Alakuko. Kini itumo oro yi? Eyi fihan pe otito ko si ninu Azikiwe ati pe ibaje ile Yoruba li okan re nlepa. Sugbon mo gbagbo pe gbogbo awon omoluwabi ile Yoruba toba-toba yio so fun Azikiwe pe "eru ko ni jogun omo ni ile Oduduwa." Azikiwe nloyun iyangbo, daju-daju, yio si bi poroporo nigbati awon ojowu ati onilara Yoruba ninu Egbe Alakuko ba so fun un laipe pe "tiwa ni tiwa; ewure ki bini k'a re iso agutan." Be li emi wi, be li yio si ri fun Azikiwe ti nfi ahon etan ko awon omo Yoruba lọ s'oko eru Ibo.


## ORIKI BAMWO



Bamwo de, alajẹja ọmọde, agbẹmọla bi orisa. Akọkọluko agun ti ada'mọlẹkun igbona, atata egun ti ap'otuju re warawara. O s'abiku d'ikugbagbe, o s'ọmọ ti ab'ebin lore. Iko ni si, Iba koo l'ona ta giri, Aiperi ni d'ẹkun iyonu. Olugbala l'ọmọ ti ayagbe ọcin. O k'apa iawo, o ta jẹdi l'alupa; gbogbo abiyamọ ayo sese. Ela ni, o ra'ja, Ọrẹrẹ ni o na 'gbe bora. Eyi npa'lẹmọ lodilẹcọ. Ọrẹ ikoko, Kojemani awọn abiyamọ, oni araiye njijadu ra.

Wa ra a lodo wa: Igo kekere 2/6d; Igo nla 4/6d.

Owo-ọkọ 1/6d. Kowe si wa fun arapọ lati gba ọdiewo.

**The Egba Trading Aradan Stores,**

144, Denton Street, 18, Denton Bridge St., P. O. Box 2, Ebute Metta. 46, Victoria Street, Lagos ati New Motor Park, Ibadan.



## FUN ESANRI, OTUTU ATI AKO-IBA

*Awọn Dọkita mọ:*




Bi ori ba nfọ ẹ, tabi otutu tabi iba, mu Phensic. Dokita ti so pe ko si egbogi kan ti o dara ju u lọ.

Phensic ni agbara ju ẹyọkan lọ, nitori egbogi alagbara mẹta ni on nikan ni. Egbogi mẹta wọnyi ngiṣẹ papọ fun iwosan kiakia ni.

Ki iṣe iwosan efori ati otutu nikan ni Phensic nse sugbọn a maa mu igbadun alafia ati inu didun wa lẹhin iwosan.

Toribẹẹ ranti re—fun ẹsanri, otutu, ati akọ-iba; awọn Dọkita ti mọ pe ko si egbogi ti o dara ju u lọ mọ




# PHENSIC

LAGBARA O SI YARA ṢIṢẸ

# Awọn Igbimọ Amuludagba ti Iwọ-Orun
## (WESTERN REGION PRODUCTION DEVELOPMENT BOARD)

### AGBARIJỌ ILE IṢẸ WA (I)

IBADAN ni a fi orirun Ile Iṣẹ Igbimọ wa fun gbogbo igbokegbodo idagbasoke ilu si. Nibẹ ni a ti le ri awọn Iriju Igbimọ ati ibiti a gbe nṣe ipade Igbimọ ati ti awọn alakoso lati ṣe ipinnu awọn ilana ati eto fun gbogbo iṣẹ wa.



Awọn Iriju ati asaju Igbimọ Amuludagba Iwọ-orun nṣe ipade

2. Titi di isisiyi, awọn ile pẹpẹpẹ ti o wa ni itosi Ile Iṣẹ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-orun ni Igbimọ fi nṣe ile iṣẹ. Ni ọdun diẹ sẹhin a fun awọn kọlekọle ara Ilu Jamani kan ni aṣẹ lati ya aworan Agbarijọ Ile Iṣẹ kan fun wa. O si ti ṣe e tan patapata nisisiyi.

3. Yio jẹ ile ti o dara pupọ ti ko l'ẹgbẹ gẹgẹbi ẹniyin na yio ti ri i ninu aworan afọwọ ya rẹ yi nigbati o ba pari. Ọpọlọpọ ile daradara ni a ti kọ kakiri agbegbe Ibadan ati pe Ile Iṣẹ Igbimọ Idagbasoke yi yio si tun ba wọn dọgba ni ni didara gẹgẹbi iru wọnyen na.

4. Awọn memba Ẹgbẹ Igbimọ Idagbasoke yi ni o nṣe eto ilana igbokegbodo awọn iṣẹ ti Igbimọ nṣe alakoso rẹ yi nwọn si tun nran wọn lọwọ fun mumuṣe Iṣẹ Idasilẹ na, awọn igbimọ alamojuto mẹfa si tun nran wọn lọwọ. Pẹlu awọn Alakoso ati awọn Igbimọ awọn oṣiṣẹ ẹlẹkọ-ijinlẹ mba ṣiṣẹ ti o ba tiya tọtun-tosi wọn gẹgẹbi eto idagbasoke ti Alaga Igbimọ, Ọgbẹni R. A. Crofts ati Gbakeji Alaga Igbimọ, Ọgbẹni A. O. Rewane nṣe lori gbogbo iṣẹ na.

5. Iṣẹ ti o wa ni Agbarijọ Ile Iṣẹ yi ni a pin si oriṣiriṣi ẹka iṣẹ wọnyi.

(a) Eto Iṣẹ Agbẹ
(b) Eto Ile Iṣẹ-owo
(d) Eto dida Iṣẹ titun silẹ
(e) Awọn Iṣiro owo
(ẹ) Awọn ẹgbẹ Ẹlẹrọ Irinṣẹ
(f) Awọn ẹgbẹ Akẹkọ Iṣẹ
(g) Elegbogi

Akọwe Agbẹ Ijọba ni yio ma a ṣe abojuto gbogbo apapọ eto iṣẹ agbarijọ Ile Iṣẹ yi.

6. Awọn oṣiṣẹ ẹlẹkọ-ijinlẹ ni o nṣe olori ninu gbogbo ẹka ile-iṣẹ wọnyi, ninu wọn mẹta wa lati Ilu Oyinbo, mẹrin si jẹ ara Naijiria.

7. Awọn eto isalẹ wọnyi yio si fun nyin ni alaye diẹ ninu iṣẹ ti diẹ ninu awọn ẹka ile-iṣẹ wa wọnyi nṣe.

#### ILE IṢẸ AGBẸ

8. Alamojuto Ile Iṣẹ Agbẹ li o nmojuto gbogbo iṣẹ to jẹ mọ gbogbo inkan ọgbin oko wa ati gbogbo ọna ti a fi ṣe iṣẹ Agbẹ. O ṣe eto fun gbogbo idasilẹ yi lati ma a gba imoran awọn ẹlẹkọ-ijinlẹ nigbati o ba yẹ, o si i daju pe nwọn nfun wọn ni oṣiṣẹ, owo, ohun elo-iṣẹ, awọn ile ikẹrusi ati awọn nkan elo ti nwọn nfẹ lati le ma a ri nkan fi ṣe iṣẹ wọn. On ni o nṣe ipinnu awọn iṣẹ ti nwọn o ma a ṣe ni ibi idasẹsilẹ kọọkan lọdọọdun ti o si sọ ọna irọrun lati ṣe e.

9. Ọpọlọpọ iṣẹ wa ni awọn ọlọgbọn ẹrọ mba wa ṣe. Awọn yi ni a npe ni awọn alamojuto (Managing Agents). Iṣẹ awọn alamojuto Iṣẹ-owo-elẹrọ si ni lati ma a ṣe iru iṣẹ bẹ e nipa iṣẹ-owo gẹgẹbi Alakoso Iṣẹ-Agbẹ ti nṣe lori gbogbo nkan ọgbin wa; nipa bayi, o ni lati wa owo fun awọn Ile Iṣẹ wọnyi nigbati nwọn ba nfẹ ẹ yio si ma a gba ẹnu wọn ṣe ni Ajọ Igbimọ Agbarijọ Ile iṣẹ wa.



Aworan afọwọya Agbarijọ Ile Iṣẹ ti a fẹ kọ pari ni Ibadan.

* * * * * *

#### ILE-IṢẸ IDASILẸ TITUN

10. A ti ri oriṣiriṣi ọpọlọpọ imoran gba nipa pe iru iṣẹ tuntun wo ni a ba da silẹ, igbakugba ni awu paapaa nro o l'aro jinlẹ. A jẹ iwa omugo lọpọlọpọ fun wa bi a ba dawọle iṣẹ kan laiko ro o wo pe boya ohun ti a fẹ ṣe yi yio ṣe e ṣe ati pe boya yio yọri si rere. Alamojuto Ile Idasẹsilẹ Titun yi pelu awọn oṣiṣẹ rẹ ni o si ni lati wa idi otitọ yi kan ki Igbimọ to wa da ohun pọ ki nwọn to dawọ le ilana iṣẹ tuntun kan. Ni ọpọlọpọ igba ni awọn ẹlẹkọ-ijinlẹ ma a nran wọn lọwọ; awọn ti o jẹ wipe nwọn ti Ilu Oyinbo wa, ni pataki ki nwọn le wa tọ wa s'ọna.

11. Irufẹ awọn nkan ti a fẹ lati mọ nipe bi awọn ohun ti a fẹ ma a ta ba le lọ o ni tita ati [illegible] ti o darajulo lati fi ibujoko iṣẹ titun na si. Bi o ba jẹ pe nipa ti awọn ohun ọgbin ni, ile ọlọra ni o dara fun un. Bi o ba jẹ pe lori awọn iṣẹ ọna ati ẹrọ ni, a ni lati jẹki lentiriki ati omi pelu mọto akero at akẹru wa ni arọwọto ile iṣẹ ibẹ. A ni lati ri i pe a ri awọn enia ti o pọ to lati lo fun awọn iṣẹ ti a fẹ lati ṣe.

12. Wọnyi ni diẹ ninu awọn iṣoro ti awọn Ẹgbẹ Odasẹsilẹ Tuntun (New Projects Department) ni lati ṣe iwadi le lori. Lẹhinna ni nwọn yio kọ gbogbo iyọrisi eto iṣẹ na silẹ nwọn a si mu u fun igbimọ pataki kan ti nwọn ti dasilẹ lati ma a fun Igbimọ Idagbasoke Iwọ-orun (Western Region Production Board) ni imọran pe ki o ma a ba awọn eto lori awọn iṣẹ titun ti nwọn fẹ lati ṣe na lọ tabi ki nwọn da a duro ni.

#### IBISẸ ETO IṢIRO OWO

13. Gbogbo awọn nkan ti o jẹ mọ eto ti owo lori gbogbo ilana awọn iṣẹ ti a nda silẹ ni a ti fi le awọn oniṣẹ iṣiro owo ti Ibudo Ile Iṣẹ (Accounts Department Headquarters) lọwọ. Biotilẹjẹpe a ni awọn ile-iṣẹ kọọkan mẹjẹ ti nwọn nṣe awọn eto owo ibi'ṣẹ wọn ti nwọn si nko wọn wa fun Ibudo Ile Iṣẹ lọsọsu. Ki i ṣe kiki ki a tete ṣe eto iṣiro owo kiakia yi nikan ni iṣẹ yi nṣe, ṣugbọn ki a le wipe ere wa lori awọn iṣẹ a fẹ na owo yi le lori ati bi owo ti a fẹ na lori awọn ilana iṣẹ na yio ṣe wa ni arọwọto nigbati a ba fẹ lo o. Eyi mu ọpọlọpọ eto dan.

14. Ki iṣe eyi nikan n... ṣugbọn Ọga-Agba awọn Onişiro-owo na ni lati ma a ṣe eto bi Ẹgbẹ ti ngnawo si ati bi owo ti wa l'apo Ẹgbẹ si ṣọwọ si Igbimọ lasẹko-lasẹko; eyi ni yio fun wa ni iṣiro iye owo ti a je na fun ọpọlọpọ ọdun si i, yio si tun ṣe eto iye owo ti a o na fun awọn iṣẹ titun ti a fẹ dasilẹ ti yio pelu ti alamojuto Ilana Eto Iṣẹ (New Projects Manager). Nipa bayi ni Igbimọ na yio fi mọ lati ṣe ipinnu bi ilana iṣẹ tuntun na ti nwọn gbe kalẹ yio jẹ sise tabi ki awọn ma ṣe e.



Awọn Iriju ati asaju Igbimọ Amuludagba Iwọ-orun nṣe ipade

*Wo eyi ewe keji...*

# Iṣẹ ọna Reluwe lọ si agbegbe Ọyọ

NI ỌJỌ Aje ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi ni Oloye A. O. Ọmọlọdun Aṣoju Ila Gusu Ọyọ ati Ẹgbẹ Afẹnifẹre ninu Apapọ Igbimọ-Nla Aṣofin Ijọba Naijiria lọ ṣe abẹrẹ lọdọ Ọgbẹni R. Innes adele Alaṣẹ iṣẹ ọkọ Reluwe pe kini nwọn ti ngbero ona Reluwe Ẹkun Ọyọ ati agbegbe rẹ si?

Alamojuto na si ṣe alaye fun Oloye Ọmọlọdun pe iṣẹ ọna Reluwe lati Ibadan lọ si Ọyọ de Ogbomọsho lọ jasi ọna Reluwe Ilọrin yio bẹrẹ ki ọdun yi to pari.

O ni ohun ti o si da a duro nipe awọn ti o wa ni sakani iṣẹ ọna lila fun Reluwe (Operational and Commercial Department) ni lati mu ayọri wiwọn ọna wa na ki awọn si fi isiro lu u ki iṣẹ na to bẹrẹ.

Oloye Ọmọlọdun si ṣe alaye fun alamojuto iṣẹ reluwe na pe biotilẹ jẹpe ọna mọto wa ni agbegbe ilu yi. wahala pupọ ni o jẹ fun wọn nitori iṣẹ moto akẹro ati akẹru ko to rara fun iṣẹ igbokegbodo ọna owo wọn, adanu pupọ ni nwọn si nri nibi ahamọ mọto. Alamojuto na si ṣe ileri ati tete bẹrẹ iṣẹ ọna reluwe na

Eyi ni ayọrisi akitiyan ijakadi ti Oloye Ọmọlọdun ti mba awọn Apapọ Ijọba Naijiria ja ninu Ile Igbimọ na ni isọwọpọ pẹlu ọgagun awọn Ẹgbẹ Alatako Ile Igbimọ-Nla na Oloye S. L. Akintọla.



Ọgbẹni Amusa Popoọla, ọkan ninu awọn Aṣoju wa ti nta awọn iwe Irohin Yoruba ati 'Daily Service' ni Kumasi Gold Coast Ọgbẹni na ni ọn ati awọn alabaṣiṣẹpọ ọn ki Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ati awọn ẹmẹwa rẹ fun ijagunmolu Ẹgbẹ Afẹnifẹre ninu idibo ẹnulọloyi

## Ogunniyi ṣe ikomọ

ESIAMA G. C.

ẸSẸ awọn enia gidi ni o pe sibi ikomọ ọmọbinrin ti Ọlọrun fi ṣike Ọgbẹni James Ogunniyi ati aya rẹ, Sarah Akankẹ Ogunniyi. Ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kejidilogun oṣu yi ni nwọn ṣe e, nwọn si sọ ọmọ na ni Elizabeth Ogunronikẹ Anikẹ Ogunniyi.

Ẹgbọn baba ọmọ na Ọgbẹni S. A. Amao ko awọn "janma" tirẹ wa lati Axim. Bi baba ọmọ na ti ngnawo ngnara ni ẹgbọn rẹ na nṣe bẹbẹ. Ọgbẹni D. O. Ọdẹlọla ko'ra kan nibẹ. Ajẹti ati amuti ni nwọn fi jijẹ ati mimu ṣe.

Awọn Ọgbẹni M. Adewọle, E. A. Larinde, S. Ajani, Raji Owolẹgbọn, S. A. Makinde, Amos A. Akanio (Aṣoju Irohin Yoruba), James Adeniyi ati Gbadamosi Arowolo wa ninu awọn alabaṣeyẹ ọjọ na.

Ire a kari o.

## Ẹgbẹ ọmọ Ijẹbu yan Oloye

ILỌRIN.

OJỌ ariya ni ọjọ Aiku, ọjọ kẹfa oṣu karun ọdun yi jẹ fun Ẹgbẹ Ọmọ Ijẹbu ti o wa ni Ilọrin nigbati nwọn yan awọn oloye ẹgbẹ wọn. Gbogbo ọmọ ẹgbẹ ti o pesẹ jẹ adọjọ.

Wọnyi ni awọn oloye ti nwọn yan:— Alaga, Ọgbẹni S. M. Osiloye; Ọbakẹji, Ọgbẹni Okẹ Oloko-Ọba; Akọwe ati Alakoso, Ọgbẹni I. O. Ọlayinka; Ọbakẹji Akọwe, Ọgbẹni J. A. Adebowaye; Akapo, Ọgbẹni H. B. Olufuwa; Akọwe Owo, Ọgbẹni M. A. Runsewe; Baba-Ẹgbẹ, Ọgbẹni Solo Aṣekun.

Ẹgbẹ yi ṣe ipinnu lati ma a wa ire ati idagbasoke gbogbo orilẹ-ede Ijẹbu ga, ki nwọn to mu ipade wọn wa si opin.

## Dokun kọmọjade

ITU

L'ENULỌLỌYI ni Ọgbẹni Solomon Dokun ṣe ikomọ ọmọ ti Ọlọrun fi ta on ati aya rẹ, Adebisi lọrẹ. Ọgbẹni John Adigun ni o ṣe eto isọmọloruko, nwọn si sọ ọmọ na ni Fajinla. Baba ọmọ na fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn alabaṣeyẹ ọjọ na lọrun.

Diẹ ti aye wa fun lati daruko ninu wọn ni awọn Ọgbẹni Joseph Ogungbinle (Alaga), Rayimi Ọladimeji, Daniel Jimoh ati Alfa Nosiru. Ire a kari o.

## Orisabandu ku

PAPALANTO.

NI ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu karun ọdun yi ni Iya oninure, Dorcas Orisabandu ku. Ero pọ nibi ẹyẹ isinku rẹ. Ẹsẹ awọn olufọkansin, awọn ọmọ ile-iwe ati ti awọn ẹgbafumọ ni o pe sibẹ.

Arabinrin Adetoro Abẹkẹ jẹ ọkan ninu awọn ọmọ marun ti ologbe na bi. Gbogbo awọn ọmọloku na ni nwọn nawo nara

Nigba aiye ologbe na, o jẹ olufọkansin. On ni Iya-Ẹgbẹ Ṣọọṣi Eronimọ Ejio. T'ọmọde-t'agba ni o ko mọra. Ki Oluwa jẹ ki ẹhin rẹ dara, ki O si fi awọn ọmọ ire gbẹhin gbogbo awọn alabaṣeyẹ isinku ologbe na.

## Ẹyẹ ikomọ ọmọ Alabi dun

ASA LẸBA IWO.

LAIPẸ ọjọ ni Ọgbẹni Ezikiel Alamu ṣe ikomọ ọmọkunrin ti Ọlọrun fi ta on ati aya rẹ, Comfort Abẹkẹ lọrẹ. Nwọn sọ ọmọ na ni Williams Oyeṣola Oluwafunmilayọ. Bi awọn obi ọmọ na ti nawo to bẹni ẹgbọn baba ọmọ na, Ọgbẹni Samuel Akinlabi fi ṣe inawo l'ọjọ na. Inawo ọjọ na buaiya o le gongo.

Diẹ ti aye wa fun lati daruko ninu awọn alabaṣeyẹ ọjọ na ni awọn Ọgbẹni Joseph Akanbi, Amos Adedunmoye, Amos Adebinpe, G. Ade Timothy Iṣọla, Reuben Adelakin ati Eman Adebayọ.





Kun.
Olerun orombo!
Egbogi mimu fun Iyagbẹ
Fun gbogbo ẹbi.

BERE
HORIZON HEALTH
SALTS
LONI!




'ANTEPAR' YIO LE GBOGBO ARUN-MUJẸ-MUJẸ INU RẸ JADE LOỌJỌ!

- 'Antepar' lo yara le arun-mujẹ-mujẹ kuro ninu
- 'Antepar' ko l'owu, bi o tilẹwu ki ọmọ kere to
- 'Antepar' dun l'ẹnu
- 'Antepar' ki i ba ni i ja ninu

Mimu rẹ lẹkan yio le gbogbo aran mujẹ-mujẹ rẹ jade l'ọganjọ!



'ANTEPAR'
ELIXIR

THE MARK OF BURROUGHS WELLCOME & CO.

Awọn Aṣoju wa ni Iwọ-Orun Afrika ni:

THERMOGENE
EGBOGI IPARA




Thermogene Egbogi ipara a ma a gbona ara pẹlu iyanu ti enia ba fi pa ara, kii si jẹki enia ṣe otutu.



Ẹ MA A
POLOWO OJA
NYIN SINU IWE
Irohin
Yoruba

## Ọlalọtiti ṣe ikomọ

ILE-OLUJI.

OGBENI Joseph Ola. Akinfiresoye se ikomọjade ọmọkunrin ti Olorun fi ta on ati iyawo re, Esther Breade lore. L'ẹnuloloyi ni nwọn se ikomọ na, nwọn si sọ ọmọ na ni Akinloye Akindayomi.

Awọn obi ọmọ na fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn alabaṣeyẹ ọjọ na lọrun. Ọgbẹni Oseni Ayandiji fi kọkọrọ ilu tẹ dabira. Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn alabaṣeyẹ ọjọ na ni awọn Ọgbẹni Joseph Ọla, Akinsulsi, . F. Akinsitande, J. Adedayọ, J. Adesọji ati B. A. Animashaun.

Ki Ọlọrun ṣe ọmọ na Yetoriire.

## Ikomọ ọmọ Arowolo dun to

ILORIN.

ESE awọn gbajumọ ni o pe sọsọ si ile Ọgbẹni Joseph Arowolo ọmọ Ilesa ni ọjọ Aiku ti ise ọjọ kejọ osu yi lati ba ko ọmọ'birin ti Ọlọrun fi ta on ati aya rẹ, Ebun Ọladunni lorẹ. Nwọn sọ ọmọ na ni Ọlabisi Oluwabukunọla.

Baba ọmọ na fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn alabaṣeyẹ na lọrun. Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu wọn ni awọn Ọgbẹni Ayọ Falokun, Samuel Ajayi, M. Olukọtun, O. Adeye, G. Ajayi Disu, I. Ọpẹtunyin ati Ẹgbẹ "St. James Catholic Church.

Ki Oluwa ṣe ọmọ na ni olori ire, ki O si fi ire kari o.

## Alaga Ogbomọshọ ko ọmọjade

KADUNA

NI ọjọ keje oṣu kẹrin ọdun yi ni Igbakeji Alaga Ogbomọṣọ Parapọ ni gbogbo Oke-Ọya ko ọmọ jade. Ẹnu kọ irohin ni ikomọ yi jẹ, ero nwọ bi omi lati ilu okere ati agbegbe.

Bi ero ti pọ to ni ọjọ na, bẹna ni o si fi jijẹ ati mimu tẹ wọn lọrun.

Ninu awọn alabaṣeyẹ na ni Baba Ogunsidina, Ọgbẹni Yesufu Bamidele, Alhaji Belo Sabogndi, Alhaji Tamko. Awọn Ọgbẹni Raji Alao, Bello Okewọle, . Ọlawuyi, S. Makinde, Solomon Akande ati J. A. Onifade.

Ire a kari o.




# Ma ṣe fi tulasi pa ẹran ọdun

### (Lati ọwọ Y. AYINLA DISU)

"ASALAM Alaiyekum" Ọdun Ileya jẹ ọdun Nla fun gbogbo Musulumi agbaiye ti nwọn ma a nṣe ni ẹẹkan l'ọdun kan. Ẹran agbo tabi aguntan tabi ewurẹ tabi malu ni a ma a npa ti a si nṣe ni ọbẹ adidun lati jẹ fun ajọyọ ọdun na, gbara ti a ba ti kirun Ọdun na tan ni gbalasa ọdan. Eyi ti olukuluku ba ni agbara rẹ ni yio pa ninu ile rẹ.

Eyi jẹ eto ti a fi mulẹ li asiko baba nla wa, Abraham nigbati o gba fun Ọlọrun lati fi ọmọkunrin rẹ, Isaku rubọ si Ọba awọn Ọba. Ọmọ na, nipa ifẹ gidi ti o ni si baba rẹ, si gba pe ki o fi on rubọ na. Bi o ti da a dubulẹ tan ti o fẹ fi ọbẹ dubu rẹ bi ẹran, ni Ọlọrun kẹ ẹ—O ṣe anu rẹ O si ta a lọrẹ ẹran agbo ki o fi dipo ọmọ rẹ. O si fi agbo na rubọ.

O pọ ninu awa "Musulumi" ti a gba Ẹsin Islam s'odi. A nfi tulasi ṣe ohun ti a ko l'agbara rẹ, a ti ohun ti ko mu tulasi dani. Tulasi ni ki a fun awọn ọmọ wa ni ẹkọ ile ki a si fun wọn ni ẹkọ iwe; ṣugbọn o pọ ninu wa ti a ko mu u ṣe.

Ki i ṣe tulasi tabi ọranyan fun Musulumi ti ko ba ni agbara lati pa ẹran Ọdun-Ileya ki o pa a. O pọ ninu wa ti a npa a nigbati ko ni agbara rẹ. Yio lọ ya owo lati fi ra ẹran ti yio pa. Bi ọdun ba ti kọja ti ko si ri owo dapada fun olowo (ẹniti o ya a), yio di alabuku, ko si ni ni ifaiyabalẹ. Aini-ifaiyabalẹ rẹ yi ki i ṣe pe adanwo Ọlọrun ni. Afọwọfa ara rẹ ni.

O tọ o yẹ ki a jina si afọwọfa. Ẹni ti o ba ni agbara lati pa ẹran Ọdun-Ileya ni ki o ra a lati pa a. Ẹni ti ko ba ni agbara rẹ ki o ma fi tulasi ṣe e. Ẹni ti ko ni agbara loni le ni l'ọla. Ki Oluwa ma jẹ ki a ṣẹku; ki O fun gbogbo wa ni alafia, owo, ọmọ ati idunnu ti a o ma a fi ṣe gbogbo ọdun ti o ba ba wal'aiye o.

Asalatu Alah Nabiyu Karim!"

# Shoyinka ba Ẹgbẹ Afẹnifẹre yọ

ILE-IFẸ

IROHIN ko to afojuba ni apejẹ ti Ọgbẹni J. O. Shoyinka, ọkan ninu awọn ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) pe ninu oṣu yi ni ile-ita-onjẹ "Milverton Hotel" fun ayọ ṣiṣẹgun ti a ṣẹgun Alakukọ (N.C.N.C.) ninu idibo ti nwọn ṣe lẹnuloloyi ni Ipinlẹ Ijọba Iwọ-Orun Naijiria. Awọn Akukọ ti a fi ori-amọ (bọta) din gbẹ ni o fi tun awọn alapejẹ ọjọ na l'ẹnuṣe.

Ninu ọrọ idunnu rẹ, o ni awọn Akukọ ti ku patapata, a si ti se wọn jẹ, nwọn ko le ji dide mọ. O ni pipajẹ ni aromọdọmọ Akukọ. Gbogbo awọn ti o pe sibi ase na bẹrẹ si yombo Awọ. Ariwo "Awo! Awo!! ati "A.G. on top" ni o gbojikan nibi ase na.

Ninu aworan yi, ẹ o ri Ọgbẹni Shoyinka ati awọn alapejẹ na, awọn Woli (Profẹt) Adesakin ati Ọgbẹni Oyelakin.



Diẹ ninu awọn enia ti o wa ba Ọgbẹni Shoyinka yọ ayọ Iṣẹgun Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni Milverton Hotel, Ile-Ifẹ ni yi.

